# Ẹ̀kọ́ Alúgórídímù

## Alúgórídímù

Nígbà tí a bá fẹ́ kọ alúgórídímù, ìgbésẹ̀ mẹ́ta ni a máa ń gbé.

**I <u>Àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́tẹ̀ta</u>**

1.1 ) **Ìgbésẹ̀ kìíní**

Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ ni kí a ṣàlàyé àwọn ohun ti a fẹ́ lò ( Àwọn oníyípadà, ìró , nọ́ḿbà..)

1.2 ) **Ìgbésẹ̀ kejì**

A máa tú ìṣòro wa sí wẹ́wẹ́ ni ọ̀nà ìpele mélòó kan. Ẹ̀yí ni a máa fún wa ni ìrọ̀rùn láti yanjú ìṣòro yìí.

<u>Àpẹẹrẹ</u>

: A fẹ́ ṣírò ( a + b ) oníyípadà a, oníyípadà b

```
tẹ  a;
tẹ  b;
d ← a+b
ìfihàn "d"; / ni orí ìbòjú
```

1.3 **) Ìgbésẹ̀ Kẹta**

Ìtẹ̀jáde àbáyọ́ ìṣòro wa, kí olùmúlò lè rí í kà.

**II <u>Kí ni alúgórídímù</u>**

**2.1 Ọ̀nà ti a fi ń lò alúgórídímù**

Alúgórídímù fẹ́ fi ara jọ ètò, àmọ́ kìí ṣe é ètò nítorí àwọn ètò ní àwọn ìtọ́sọ́nà ( kóòdù ) ti a ń lò fi kọ wọn.

Alúgórídímù kò níí àwọn ìtọ́sọ́nà ( kóòdù ) kan pàtó. Olùmúlò gan-an ni a á kọ àwọn ìtọ́sọ́nà ( kóòdù ) láti fi ètò sí èrò rẹ, àti fi rí ọ̀nà àbáyọ fún ìṣòro rẹ.

## 2.2 **Báwo ni a ń kọ alúgórídímù ?**

Ètò : orúkọ ètò náà

Oníyí: oníyípada1, oníyípada2 ... : ohun ìṣẹ̀dá

**Ìbẹ̀rẹ̀**

ìtọ́sọ́nà 1 ;

ìtọ́sọ́nà 2 ;

ìtọ́sọ́nà 3 ;

**òpin**

## 2.3 Àlàyé àwọn ohun èelò

### 2.3.1 Àwọn ohun èelò ìpìnlẹ̀

Àwọn èyí ti a ń lò fún àwọn ètò ìkójọpọ̀ ( C, C++, cobol, java...).

Àwọn ìwọ̀nyìí ni : ìró, àsòpọ̀-iró, nọ́ńbà rere, nọ́ńbà òdì, alákómejì, àtẹ.

### 2.3.2 ìró

Àwọn wọ́nyìí ni àwọn ìró fáwẹ̀ẹ̀lì, kọ́ńsónáńtì, nọ́ńbà, àti àwọn omìíran... Báítì ni àṣojú wọ́n, báítì kan jẹ́ ìró kan.

### 2.3.3 Àsópọ̀-ìró

Àwọn àsópọ́ ìró yìí ni máa ń ṣàpèjúwé ohun ti a fẹ́ sọ.

Àpẹrẹ ilé, ìlú, ìyá ...

### 2.3.4 Alákóméjì

Àwọn oníyípàdà tí máa ń ní ojú méjì ("ojú" , "òdì" ) tàbí ("òdo", "òótọ́") tàbí pẹ̀lú àwọn nọ́ńbà ("0", "1").

### 2.3.5 Nọ́ńbà

Àwọn  wọ̀nyìí ni odò, nọ́ńbà òdì, nọ́ńbà rere ;

Àpẹrẹ :

Nọ́ńbà òdì :  -1, -2, -3, -4, -5, .........

Nọ́ńbà rere : 0, 1, 2, 3, 4, 5, ...........

### 2.3.6 Nọ́ńbà gidi rere

Apẹrẹ   1.2, 25.412,   452.478 .....

### 2.3.7  Nọ́ńbà gidi òdì

Apẹrẹ   -1.2, -25.412,   -452.478 .....

### 2.3.8 Àtẹ

Inú àtẹ yìí ni a máa ń kó àwọn ohun èelò ti ó jọ́ra wọn sí, ti a sì fún ni orúkọ tó jẹ́ orúkọ àtẹ, tí á so mọ́ orúkọ àwọn atọ́ka nọ́mba.

oníyí orúkọ(b1 ,b2): nọ́ńbà

**Àpẹẹrẹ**

TA

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1 | 2 | 3 | 0 | 4 | -1 |

### 2.3.9 Ohun ọ̀wọ́

Àwọn ohun ọ̀wọ́  ni àwọn ohun ìpìnlẹ̀ tí  a sopọ̀ fi ṣẹ̀dá ẹ.

Ohun ọ̀wọ́ orúkọ= (........, ........, ........ )

Àpeere

Ohun ọ̀wọ́  ọlùkọ= ( nomba : nọ́mbà, orukoakoko : àsopọ̀ iró, orukoidile: àsopọ̀ iró )

## 3 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìpìlẹ̀

### 3.1 Ìtọ́sọ́nà fi sí

Ìtọ́sọ́nà yìí ni a máa ń lo fi fi ohun èelò sínú oníyípadà. Àmì ọ̀fà ni a mán ń lo fi kọ ìtọ́sọ́nà náà.

< oníyípadà > ← < ohun èelò >

<u>Àpẹẹrẹ</u>

a ← 3;

Oruko ← “Ade”;

### 3.2 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìwọlé àti ti ìjáde

#### 3.2.1 Ìtọ́sọ́nà Ìwọlé

Ìtọ́sọ́nà Ìwọlé ohun èelò ni a máa ń lò fi fi ohun èelò yìí sínú ìranti ẹ̀rọ kọ̀ńpútà ( ẹ̀rọ ìtẹwé kọ̀ńpútà ) ni **tẹ**. A á lò oníyípadà fi gbé ohun èelò ti a tẹ̀ pamọ.

tẹ < ohun èelò >

Àpẹẹrẹ tẹ a.

#### 3.2.2 Ìtọ́sọ́nà Ìjáde

Ìtọ́sọ́nà Ìjáde ohun èelò máa jẹ́ kí a kọ ọ́ sórí ìbòjú kọ̀ńpúta kí olùmúlò lè rí í kà. Ìtọ́sọ́nà náà ni **ìfihàn**

**ìfihàn** < ohun èelò >

Àlàyé àwọn oníyípadà

Kí a tó lò àwọn oníyípadà a ni láti ṣàlàyé wọn , báyìí ni a ń ṣe é.

oníyí orúkọ-oníyípadà : ohun èelò

A lè kó àwọn oníyípadà kannáà pọ̀ sínú ìkójọ kan.

Àpẹẹrẹ

oníyí i, j, k : Nọ́mba

## 4 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣiṣẹ́

Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso alúgóridímù ètò ni a ń lo fi ṣé wọn.

### 4.1 Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkosó

Ìwádìí àwọn ọjọ́gbọ̀n fi yé wa wí pé a lè kọ alúgóridímù ètò pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà ìṣákóso mẹ́ta, a máa ń pè àwọn wọ̀nyìí ni ìtọ́sọ́nà ìpìnlẹ̀ .

Àwọn mẹ́tẹ̀ta ni :

- lẹ́sẹẹ̀sẹ
- Àlátúnṣe
- Omìíran

#### 4.1.1 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso lẹ́sẹẹ̀sẹ

Àwọn ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso wọ̀nyìí máa ń fún wa ni àǹfààní láti kọ àwọn ìtọ́sọ́nà sínú ìkójọ kannáà, a kọ àkọ́kọ́ sẹ́yin èkejì, èkejì sẹ́yin ẹ̀kẹ́ta... bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

```
Ìtọ́sọ́nà 1
Ìtọ́sọ́nà 2
Ìtọ́sọ́nà 3
................
```

#### 4.1.2 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso omìíran

Àwọn ìtọ́sọnà ìṣàkóso wọ̀nyìí ni a máa ń lò tí a bá fẹ́ lò ìtọ́sọ́nà kan tàbí omìíran. Ajẹmọ́-kání ni máa ń tọ́ wa sọ́nà.

Báyìí ni a ń kọ wọ́n.

```
Nígbà tí ( ajẹmọ́-káni = "òótọ" )
    Ìtọ́sọ́nà 1
bkbrb
    Ìtọ́sọ́nà 2
Òpintí
```

**bkbrb** : bí kò bá rí bẹ́ẹ̀.Àwọn ìtọ́sọ̀nà ìṣàkóso mì ín

**4.1.2.1 Kúkúru**

Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso yìí máa wò ó tí ajẹmọ́-kání bá jẹ́ “òótọ” tàbí “òdo”.
A máa ń kọ ọ́ báyìí

```
Nígbà tí ( ajẹmọ́-kání =    “òótọ́” )
    Ìtọ́sọ́nà
Òpintí
```

Tàbí

```
Nígbà tí ( ajẹmọ́-kání = “òdo” )
    Ìtọ́sọ́nà
ÒpinTí
```

**4.1.2.2 Gbọ̀ọ́rọ**

```
Pínnu nínú
        Nígbà tí      ajẹmọ́-kání 1 :
          Ìtọ́sọ́nà1
        Nígbà tí      ajẹmọ́-kání 2 :
         Ìtọ́sọ́nà2
        Nígbà tí      ajẹmọ́-kání 3 :
         Ìtọ́sọ́nà3
        ........................
         Omìíràn
        Ìtọ́sọ́nà4
ÒpinÌpínnu
```

## 4.2 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso aláṣetúnṣe

Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso ètò yìí ni a máa  lò fi tún àwọn ìṣe ṣe.

Ajẹmọ́-kání ni ìtọ́sọ́nà àtúnṣe yìí máa ń lò fi mọ́ ti a bá dá ìṣe dúro tàbí ti a bá máa ba ìṣe lọ.

Nígbà ti ẹ bá máa kọ alúgórídímù yín, ẹ ro májẹ̀mu ti ẹ máa lò, bí kò bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ ìṣe yín kò níí dúró títí ayérayé.

Àwọn ìṣàkóso aláṣetúnṣe méjì ló wà:

- Aláṣetúnṣe “ìjáde òkè”
- Aláṣetúnṣe “ìjáde ìsàlẹ̀”

### 4.2.1 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso aláṣetúnṣe “ìjáde òkè”

Báyìí ni a ń kọ wọn

```
Nígbà Tí ( ajẹmọ́-kání aláṣetúnṣe ) = “òótọ́”
|
|              Ìtọ́sọ́nà 1
|              Ìtọ́sọ́nà 2
|              ...........
|              Oníyípadà  “ ìtọ́sọ́nà ìṣákóso “
|
Òpin Nígbà Tí
```

## 4.3  Aláṣetúnṣe “ìjáde ìsàlẹ̀”

Báyìí ni a ń kọ wọn

```
Túnṣe
|
|              Ìtọ́sọ́nà 1
|              Ìtọ́sọ́nà 2
|              ...........
|              Oníyípadà  “ ìṣákóso “
|
Títí ( ajẹmọ́-kání ìjáde ) = “òótọ́”
```

## 4.4 Ìtọ́sọ́nà ìṣàkóso Fún

A máa ń lò ìṣàkóso Fún nígbà ti a kò bá fẹ́ lò ìṣàkóso àtúntúnṣe.

Báyìí ni a ń kọ.

```
Fún    I  kúrò ni d dé  f  ẹ̀sẹ̀ p  ṣé
|
|          Ìtọ́sọ́nà
|          .............
|
ÒpinFún
```

Àdáṣe

Ìṣírò   1 + 2 + 3 + 4 + 5 + 6   pẹ̀lú kọ̀ńpútà.

ÈSÌ

Ètò : Àfikún àwọn nọ́mbà

oníyí :  i,s,n : Nọ́mbà

```
Ìbẹ̀rẹ̀
|
|         I ← 0
|         s ← 0
|       Nígbà Tí   ( i < 7 )  ṣe
|       |
|       |      s ← s + i
|       |      i ←  i + 1
|       |
|       Òpin Nígbà tí
|
|         ìfihan   “ s ”
|
Òpin
```